# ỌNÀ ÌFẸ́

**Ìwé pelebe lórí ojúlówó ìtumọ̀ ìfẹ́,**

**Èrèdí ìṣe ẹ̀mí tòótọ́**

**Ẹ̀mí ore – ọ̀fẹ́ àtòkèwá**

**Srila Bhaletivedanta**

**Naraya Gosvami: Maharaja**

# ÌMỌ RÍRÌ

Mo bẹ̀bẹ̀ fún ànú aṣíwájú mi Gurudava, nityalila Pravista am Visnupada Sri SrimadBhakri Prajaana Kasava Gosvami Maharaja. Mo. Ẹgbẹgbẹ̀rún ọ̀wọ̀ àti ìtẹríba lábẹ́ ẹsẹ̀ rẹ̀ àti ìtẹríba kanna ní abẹ́ ẹsẹ̀ ọ̀gá mi Siksa – guru, nitya- lila pravista.om risnupada Sri Srimad Bhaktivadanta Svami Maharaja.

Ní ọjọ́ òní ọ̀gá mi Siksa guru ni ó ṣí ilẹ̀kùn ìṣura ọgbọ́n fun mi fun gbogbo ayé. Kọ́kọ́rọ́ sí ìṣúra wà ní ọwọ́ rẹ̀ ati ní ọwọ́ Gurudava mi. Wọ́n ti fun mi ni kọ́kọ́rọ́ wọn, wọ́n sì ti wípé kí nfi ìṣúra na hàn fún gbogbo yín.

**Tri dandi – bhiksu Sri Bhakrivedanta Narayana**

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ló lọ́wọ́ sí títẹ ìwé yì jáde gẹ́gẹ́bi akọ́ṣẹ́ mọṣẹ́ òntẹ̀wẹ́, olùgbaninímọ̀ràn ìwé kíkọ, àwọn ayàwòrán, atẹ̀wé, ònkọ̀wé sílẹ̀, akàwé àti àwọn olùrànlọ́wọ́ míràn. Àwọn bi Sripada Bhaktivedanta Madhara Mahraji, Sripada Bhakfi Vedanta vaikhanas Maharaja, Atula-krisna dasa, Anita dasa, Bhadhara dasa, Brajanatha dasa, Dhanenjaya dasa, Giridhari dasa, Gauragi dasi, Guruttana dasa, Jaya-gopala dasa, Mahaprabhu dasa, Nanda – kisara dasa, Nandimu khidasi, Nandini dasa, Premarata dasi, Radha-kanta dasa, Santi dasa, Sudarsana dasa, Sundara- Gopala dasa, Syamarani dasi, Vayajayanti- maladasi, vasantidasi ati Visvanbhara dasa.

Ọpẹ́ Pàtàkì fún gbogbo àwọn alágbàtà ìwé fún ìrànlọ́wọ́ tí wọ́n nṣe láti pín ìwé yi kárí àwọn tí wọ́n nkàá.

# ÀWỌN ÀKÒRÍ INÚ ÌWÉ YÌ


Ọ̀rọ̀ Àkọ́sọ ………………………………………………………………. 1

Ìfẹ́ ayé òdì ………………………………………………………………. 5

Ẹbí kan ṣoṣo ló wà ……………………………………………………

Ìrẹ́pọ̀ nínú onírúurú ………………………………………………….

Ní ìfẹ́ gbogbo ẹ̀dá …………………………………………………….

Ìfẹ́ ní bí ó ti rí …………………………………………………………

Láìsí ìfẹ́ náà …………………………………………………………..

Wíwá ìdùnnú …………………………………………………………….

Ìbéèrè tí ó pé ………………………………………………………….

Ipa ọ̀nà sí ìdùnnú ……………………………………………………..

Ẹwà èdè ìfẹ́ àtòkèwá …………………………………………………..

Ibití a wà ní àgbáyé àti ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ wa ………………………………..

# ỌRỌ ÀKỌSỌ

Èrèdí ìwé yi ni láti fihàn àwọn ọrọ àwọn tí wọn ti mọ òtítọ mímọ ti a fi hàn nínú àwọn ìwé mímọ àtijọ ti India tí à npè ní Vedas. Gbólóhùn Védà túmọ si "Òpin gbogbo àkòrí ọrọ tí ó jẹ mọ ayé tí ó nyí padà àti gbogbo ọrọ tí ó jẹ mọ ayé yì, yálà èyí tí ó ṣe Pàtàkì tàbí èyí tí kò ṣe Pàtàkì.

Védà di kíkójọpọ ní àwọn ẹgbẹrún ọdún sẹhìn láti ọwọ àwọn tí wọn pe ara wọn ní ẹni mímọ tí ọkàn wọn kún fún ìfẹ àwọn tí ó njìyà láyé yì. Àwọn ẹni mímọ wọnyí ní òye òtítọ tí ó pé tí ó sì ga jùlọ àti èrèdí ìgbé ayé . Ọnà ìfẹ jẹ àkọsílẹ àwọn ìfọrọwé ọrọ àwọn ẹni Pàtàkì gẹgẹbí ẹni ọwọ Srila Bhaktivedenta Narayana Gosvami Maharaja, ẹnití ìgbé ayé rẹ jẹ ìfarajì àìyẹsẹ fún ìdùnnú àwọn ẹlọmíràn.

Nínú àwọn àkọsílẹ yí, a fẹ fi hàn wá, àwọn ọrọ, ẹni mímọ míràn, Srila Bhaktivedanta Svanu Maharaja, ẹnití ó jẹ gbajúmọ ní gbogbo ayé gẹgẹbí Srila Prabhupoada ẹnití ó ní àjọṣepọ pẹlú Srila Novayana Gosvami Maharaja gẹgẹbí olùkọ tó mòye àti ọrẹ tímọtímọ. Srila Narayana Gosvami Maharaja gba Srila Bhakti redanta Sramu Maharaja gẹgẹbí ìwúrí fún ìrìn àjo rẹ kákiri gbogbo ayé tí ó sì nṣe ìdánilẹkọ lórí ọnà ìfẹ. Srila Bhaktivedanta Svami Maharaja ṣe àkọsílẹ yí:

"Ìgbékalẹ ìgbé ayé dá lórí wípé a níláti ní ìfẹ sí ẹnìkan. Kò sí ẹnití ó lè wà láyé láì fẹràn ẹnìkan. Ìfẹ yi wà nínú gbogbo ẹdá ènìyàn. Ẹranko gẹgẹbí àmọtẹkùn gan ní irú ìfẹ yì, irú èyítí ó wà nínú ènìyàn. Iṣẹ ibẹ wá ni wípé, níbo ni a ó darí ìfẹ wa sí èyítí yío mú inú gbogbo ènìyàn dùn. Báyì, àwùjọ ènìyàn nkọ wa láti fẹràn orílẹ-èdè , tàbí ẹbí, tàbí ara ẹni, ṣùgbọn kò sí ọrọ lórí níbo ni a lè darí ìfẹ wa sí fún ìdùnnú gbogbo ènìyàn.

Ní ìbẹrẹ, ọmọdé yío fẹràn àwọn òbí rẹ, lẹhìnnà, àwọn arákùnrin àti arábìrin rẹ, bí ó sì ti ndàgbà, yío bẹrẹ sí fẹràn àwọn mọlẹbí, àwùjọ, agbègbè, orílẹèdè, ẹyà tàbí àwùjọ ènìyàn. Ṣùgbọn ọkàn láti fẹràn kò ní ìtẹlọrùn pàápà ní àwùjọ àwọn ènìyàn. Ọkàn láti ní ìfẹ yi kò lè pé àyàfi tí a bá mọ ẹnití ẹlẹdà fẹràn. Ọkàn ìfẹ wa ngbòrò si gẹgẹbí ìmọlẹ tàbí atẹgùn, ṣùgbọn a kò mọ ibití ó parí sí.

Srila Bhaktivedanta Suami Maharaja nṣe àlàyé síwájú si ìṣòro tí ó nkojú wa- àìmọ bí a ti ṣe lè fi ìfẹ hàn. Ó ṣe àlàyé ìmọ ìjìnlẹ níní ìfẹ pípé sí gbogbo ènìyàn nípa ìlànà níní ìfẹ sí ẹlẹdà tí a mọ nínú Védàs gẹgẹbi Krsna:

"A ti kùnà láti ṣe ìgbékalẹ Àláfíà àti ìrẹpọ ní àwùjọ ènìyàn, bí àwọn àjọ àgbáyé tilẹ ti gbìyànjú tó, nítorí àwa kò mọ ọnà tí ó tọnà. Ọnà náà kò tilẹ le rárá.

“Tí a bá mò lati ní ìfẹ̀ Krsna, nigbana yio rọrùn lati ní ìfẹ́ gbogbo ẹ̀dá lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀. Ó dàbí omi tí a dà si orí gbòngbò igi tàbí fun inú ni ounjẹ. Ìlànà láti da omi sí gbòngbò igi tabi fun inu ní ounjẹ jẹ́ ohun tí ó kárí ayé ti gbogbo eniyan sì nní ìrírí rẹ̀. Gbogbo eniyan mọ̀ pé nígbàtí a bá jẹun sí inú, agbára tí ó ti ibẹ̀ wá yio kárí gbogbo ara. Bakanna tí a bá da omi sí ara gbòngbò igi, agbara tí yio ti ibẹ̀ wá yio kárí gbogbo ẹ̀yà ara igi na. ko ṣee ṣe lati bu omi sí ẹ̀yà ara igi lọ́tọ̀ọ̀tọ̀”.

“Ìpìlẹ̀ àiní ìtẹ́lọ́rùn wá ni wipe, ìfẹ́ inú wa tí kò hàn síta kò ní ìtẹ́lọ́rùn pẹ̀lú gbogbo itẹsiwaju ati awọn ohun mèremère aye. Gbogbo ẹ̀yà ara igi ni a ma nbu omi sí ṣugbọn a wá yọ gbòngbò rẹ̀ sílẹ̀. A gbìyànjú láti mú àgọ́ ara wa wà ní ìlera ni gbogbo ọ̀nà tí a wá ndágunlá sí fífi ounjẹ sí inú wa.

“Ìpàdánù ìṣẹ̀dá wá túmọ̀ sí ìpàdánù ara ẹni pẹ̀lú ìwára – ẹni rí àti ìdánimọ̀ ọkàn ìṣẹ̀dá tí a mọ̀ sí Oluwa Sri Krsna, tí Í ṣe ẹwà agódo ìfẹ́ nlo papọ̀ ni. Fún àpẹrẹ , rírí ara rẹ ní òwúrọ̀ túmọ̀ sí rírí ìlà oòrùn pẹ̀lú; láìjẹ́ pé òòrún ràn, iwọ kò le rí ara rẹ. Àwọn ìbáṣepọ̀ ọkàn tí ó fi ìdí kalẹ̀ nínú ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú aṣẹ̀dá ọkàn jẹ́ àṣepọ̀ tí ó dájú. Àjọṣepọ̀ ara jẹ́ orísun ìdè ohun ti ara, ṣugbọ́n ìbáṣepọ̀ ti ọkàn ni okùnfà òmìnira. Ìbáṣepọ̀ ọkàn pẹ̀lú ọkàn lè fi ìdí múlẹ̀ ní abala ìbáṣepapọ̀ ọkàn tí ó ga jùlọ. Ìríran nínú òkùnkùn kìí ṣe ìríran. Ṣùgbọ́n rírí ninu ìmọ́lẹ̀ oòrùn túmọ̀ sí rírí oòrùn àti àwọn ohun míràn tí a kò lè rí ninu òkùnkùn”

Bí ó ṣe jẹ́ òtítọ́ nínú lítíréṣọ̀ Vedic, ìwé yi wà láti kọ́ wa láti “tan ohun kan èyí tí yío tan ìmọ́lẹ̀ sí ohun gbogbo ni ibi gbogbo” Gbogbo awọn ìtàn tí a sọ níhìn wáyé nítòótọ́. Srila N arayana Gosvami Maharaja ti mú wọn láti ara Vedas ti a mọ̀ sí Puranas ati Upanisads.

Àwọn orúkọ tí a da nihin jẹ́ ti èdè Sanskrit atijọ. Ní títẹ̀lé àṣà àwọn aṣíwájú wa ninu ẹ̀mí, a lo àwọn èèyán àmì tí ó péye láti lè pe àwọn ọ̀rọ̀ Sanskrit wọ̀nyí dáradára.

Akọ̀wé.

ỌNÀ ÌFẸ́

Ìfẹ́ àyè òdì.

Ní ìgbà kan, ọ̀dọ́ ọba kan wà èyítí ó yẹ, tí ó sì rẹwà tí orúkọ rẹ̀ njẹ́ Bhartrihari, tí ó mọ iṣẹ́ ọnà. Ọba Bhartrihari gbé ìyàwó ní ọmọ ọdún mẹ́ẹ̀dọ́gbọ̀n tí ó sì ṣe aya àṣẹ̀ṣẹ̀gbé rẹ̀ ní ẹ̀ṣọ́. Ó ní ìtara láti tẹ lọ́rùn, Ó fun ní ẹ̀bùn ẹ̀gbà ọrùn oníyebíye. Ó fi ọwọ́ ara rẹ̀ fi ẹ̀gbà nà si ni ọrùn. Ó fàá mọ́ra, ó wípé, "Olùfẹ́ ọ̀wọ́n tí ó tayọ jùlọ, ẹgbà ọrùn yí jẹ́ iyebíye. Jọ̀wọ́ tọ́jú rẹ̀"

Ọba Bhartrihari ní ìfẹ́ aya rẹ̀ púpọ̀, ṣùgbọ́n aya rẹ̀ kò ní irú ìfẹ́ bẹ́ẹ̀ sí ọkọ rẹ̀. Dípò bẹ́ẹ̀, adari ogun ọkọ rẹ̀ ni ó ní ìfẹ́ sí, èyítí ó lẹ́wà lọ́pọ̀lọpọ̀. Nípa bẹ́ẹ̀ lẹ́hìn ọjọ́ díẹ̀ tí ó gba ẹ̀bùn ẹ̀gbà ọrùn iyebíye yi, ó fún adari Ológun ọkọ rẹ̀ yí gẹ́gẹ́bí àmì ìfẹ́ si.

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ayaba yi nífẹ̀ sí adarí Ológun yi, òun ní tirẹ̀ kò ní irú ìfẹ́ bẹ́ẹ̀ si. Ó ní ìfẹ́ sí oní ṣìná. Lẹ́hìn ọjọ́ díẹ̀ tí ó gba ẹ̀bùn ẹ̀gbà ọrùn yí, ó fún oní ṣìná gẹ́gẹ́bí ẹ̀bùn gẹ́gẹ́bí àmì ìfẹ́ si. Oní ṣìná yi kò ní irú ìfẹ́ sí adarí Ológun yi bíkòṣe sí ọba. Ní ọjọ́ kan, ó fún ọba ní ẹ̀bùn ẹ̀gbà ọrùn nà gẹ́gẹ́bí àmì ìfẹ́ sí ọba . Nígbàtí ọba rí ẹ̀gbà ọrùn na, inú rẹ̀ bàjẹ́, ó bèrè lọ́wọ́ rẹ̀ ibití ó ti ríi. Ìbẹ̀rù kò jẹ́ kí ó lè dáhùn. Pẹ̀lú ìbínú, ọba wípé "èmi yío gé orí rẹ tí o bá kùnà láti sọ òtítọ́" oní ṣìná na wá sọ òtítọ́ na fún ọba, ẹnití ó fi sílẹ̀ tí ó sì mú ẹ̀gbà ọrùn na tọ adarí ọmọ ọgun lọ. Ọba Bhartrihari bèrè lọ́wọ́ olórí ogun rẹ̀ wípé "níbo ni ó ti rí èyí?" Tí o bá sọ òtítọ́ fún mi, èmi kò ní pa ọ́ lára, àìjẹ́bẹ̀ èmi yío gé orí rẹ"Olórí ogun nà sọ òtítọ́ fun, báyì ni ọba ṣe mọ̀ pé kò sí ìfẹ́ tòótọ́ mọ́ ní ayé yì. Lẹ́sẹ̀kẹ́sẹ̀ ló pinnu láti gbàgbé gbogbo àsopọ̀ rẹ̀ láyé. Ó fi àfin, ìjọba àti aṣọ ọlọ́lá rẹ̀ sílẹ̀ ó wá di gbajúgbajà ẹni ẹ̀mí.

[Ìbànújẹ́ àti ìbínú ọba Bhartrihari ti inú ìfẹ́ rẹ̀ tí ó bàjẹ́ jáde wá. Ohun tí ó ṣe okùnfà èyí ni wípé kò mọ̀ pé láti ní ìfẹ́, o níláti kọ́kọ́ tẹ́wọ́gba ìfẹ́ èyítí ó ga jùlọ. Ìdàmú tí o tọ́wò wáyé nítorí àìní òye ìfẹ́ tí ó ga jùlọ, Ọlọ́run èyítí ó wà lọ́pọ̀ láyé yi. Lára wa rò wípé kò sí, àwọn kan rò wípé kò ní atọ́ka wípé kò ní àmúyẹ, tí àwọn míràn sì rò wípé onírúurú Ọlọ́run ló wà fún àwọn onírúurú ẹ̀sin. Ìwọ̀nyí ṣe ìfihàn bí ẹnikẹ́ni ṣe lè gba òmìnira lọ́wọ́ gbogbo ìjiyà tí ìbínú, owú jíjẹ àti ìjà má nmú wa nípa mímọ òtítọ́ ẹ̀mí kan- ed]

## ẸBÍ KAN ṢOṢO NI Ó WÀ

Gbogbo wa ló wà nínú ẹbí kan nà èyítí Í ṣe ti Ọlọ́run. Kìí ṣe pe Ọlọ́run kan wa ní ìlú òyìnbó, tí òmíràn sì wà ní orílẹ̀ èdè Àmẹ́ríkà, tí òmíràn sì wà ní orílẹ̀ èdè India. Àwọn krìstẹ́nì, mùsùlùmí ati Hindu kò sin Ọlọ́run ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀. Àwọn orúkọ gẹ́gẹ́bí Allah, Brahma, Jehofa, Krsna ati Yahweh nsọ nípa Ọlọ́run kanna tí wọ́n npè ní orúkọ ọtọ̀ọ̀tọ̀ ní ìbámu pẹ̀lú oniruuru èdè àti àṣà wọn.

Tí a bá fẹ́ràn Ọlọ́run kanna, kíló wá fa ìjà? Ìjà nwáyé nítori òye ojúlówó ìfẹ́ kò yé wa. Ti a ba ni ìfẹ́ tòótọ́ ati ìfẹ́ fun olúwa kanna, ó yẹ kí a fẹ́ràn ara wa ní tààrà. A ma npèdè kan wipe "Ọlọ́run ni ìfẹ́, ìfẹ́ ni Ọlọ́run" Bẹ́ẹ̀na ni ninu àṣà India, Vedic a ma npèdè kan wipe "Inu gbogbo wa nilati dun"

Jesu paapa ni òye ìrònú yi. O lọ́ si India nigbati ó pé ọmọ ọdún mẹ́rìndínlógún, o bẹ ọ̀pọ̀lọpọ̀ ilẹ̀ mímọ́ wò gẹ́gẹ́bí Venadavana, Ayodhya, gúsù India ati Jagannatha Puri. Ni puri, ó rí awọn òrìṣà Jagannatha, Baledava ati Subhadri, o si gbọ́ ohun olúwa Jagannatha (ti itumọ̀ rẹ̀ njẹ́ "Olúwa àgbáyé)" tí wọ́n npè ní Krsna. Ní apá India yi, Krsna kanna ni wọ́n npè ní Kroosna. Nítorí ìyàtọ̀ nínú èdè Griki ati Hébérù, orúkọ yi wá di kroosta ati krista nígbàtí ó yá, ṣùgbọ́n báyì, a wá npe ní Kristi. Krsna, kroosna krisa báyì Krístì- gbogbo ìwọ̀nyí jẹ́ ọ̀kan nà.

Ní ayé yi, Ọlọ́run kanṣoṣo ni o wà, kìí ṣe ará Russia, oyinbo, Gamani tabi Spain. Ó gbọ́ gbogbo èdè láìsí wàhálà. Èdè ẹyọ kan ṣoṣo ló wà ni gbogbo àgbáyé, èdè ná ni à npè ní ìfẹ́. Ojú lè sọ èdè na, àwọn etí àti ọwọ́ lè sọ̀rọ̀ kí ó sì yé wọn, ojú tí ó ntan ìmọ́lẹ̀ le sọ ohun gbogbo, ọ̀kan ni Ọlọ́run, ara rẹ̀ sì ni ìfẹ́ parí sí. Orúkọ Ọlọ́run gan ni Krsna ti a fun ni Vedas àtijọ́ tí ìtumọ̀ rẹ̀ njẹ́ "agódo ìtura tí gbogbo ènìyàn nlọ sí". Àwọn orúkọ ìyókù gẹ́gẹ́bí ọkàn alágbára jùlọ, Buddha, Allah ati Ọlọ́run wà nínú RẸ̀.

## ÌRẸ́PỌ̀ NÍNÚ ONÍRÚURÚ.

Bí a tilẹ̀ ti jẹ́ ẹ̀yà àti ara Olúwa àgbà kanna, a ti pín ayé yì, pẹ̀lú ìkéde, "Orílẹ̀-èdè mi ni èyí! Orílẹ̀ -èdè rẹ ni èyí!"

Bi a tilẹ̀ jẹ́ olóòtọ́, a gbẹ́kẹ̀lé Ọlọ́run kanna tí a sì n mí atẹ́gùn kannà sí inú. Èyí ni igbékalẹ̀ ìrẹ́pọ̀ nínú onírúurú. Ìrẹ́pọ̀ tọ́ka si wípé a jẹ́ ẹ̀yà ati ara olúwa àgbà Krsna kanna, baba gbogbo eniyan; tí oniruuru sì tọ́ka sí ìṣẹ̀dá ayeraye ẹnikọ̀ọ̀kan. Nítori eyi jẹ́ òtítọ́ ayeraye, ao ni Alafia ati idunnu ninu otitọ yi. Irẹpọ ninu oniruuru kò ní ìtumọ̀ tí àwọn eniyan kò bá ni ìgbàgbọ́ ninu Ọlọ́run tí ó ga jùlọ, tàbí ní ìfẹ́ RẸ̀ ati gbogbo ẹ̀dá.

NÍ ÌFẸ́ GBOGBO ẸDÁ.

Ní igbagbogbo ni a ma nro pe àwọn eniyan nikan ni ọmọ ẹbí Ọlọ́run, ṣugbọ́n èyi jìnà sí òtítọ. Oun ni adẹ́dà gbogbo ẹ̀dá. Ọmọ rẹ̀ ni gbogbo wọn jẹ́, nipa bẹ̀, kíni kò fi yẹ kí a fẹ́ràn gbogbo wọn? Ede wipe "Inu gbogbo eniyan nilati dùn" kò túmọ̀ si ẹ̀dá eniyan nìkan.

Oluwa ti o ga julọ lo da awọn màlù, ti àwọn màlú wọ̀nyí sì nfún gbogbo ènìyàn ní wàrà lọ́fẹ̀. Ni Vedas, a npe màlù ní go mata, ìyá fún màlù, nitori ó nbọ́ wa pẹ̀lú wàrà rẹ̀, kò sí ní àkọsílẹ̀ nínú bíbélì wípé o lè pa màlù tàbí ẹranko míràn. Ni atetekọṣe èdè Aramaic ti Bibeli, a lo ọ̀rọ̀ "brosimus" ju ìgbà ogún lọ. "Brosimus" túmọ̀ sí "Ounjẹ" ti a tumọ sí "ẹran". Ni ede oyinbo atijọ, "ẹran" kò túmọ̀ sí "Ẹran ara" bikoṣe "Ounjẹ". Ṣùgbọn ede oyinbo ti yàtọ̀, lónì ọ̀pọ̀ eniyan nṣe àṣiṣe láti Gbàgbọ́ pé Bibeli mimọ́ fi ara mọ́ jíjẹ ẹran ara ẹranko.

Májẹ̀mú lailai sọ yékéyéké wipe, "ìwọ kò gbọ́dọ̀ pa ènìyàn". Èyí túmọ̀ sí pé ki o máṣe pa ènìyàn tàbí ẹranko. Kùránì kò fọwọ́ sí pípa àti jíjẹ ẹran malu. Oluwa àgbà kò dá ẹranko fún wa láti jẹ. Nítorí èyí, ó da àwọn èso, gbòngbò, wàrà, ọ̀rá, ati ewébẹ̀. Inú rẹ̀ yío bàjẹ́ tí a ba pa eyíkéyì àwọn ọmọ rẹ̀ lára, kini yío sọ tí a bá wa pa iyá wa.

Awọn igi, àfòmọ́, túùpú àti àwọn kòkòrò pẹ̀lú jẹ́ àwọn ọmọ RẸ̀. Nínú àṣà India Vedic, wọn ma nsọ wípé ẹnikẹ́ni kò gbọdọ̀ rìn lórí ilẹ̀ tí a bá gbin nkan ọ̀gbìn sí nitori àwọn irúngbìn na lè kú. A kò gbọ́dọ̀ fa ìrora àti ìjìyà bá ohun ẹlẹ́mì Kankan.

Gbogbo wa ni ọmọ olúwa àgbà, ẹnití ó duro fun idunnu ati agódo ayọ̀ ti o ga jùlọ fún àwọn ẹlòmíràn. A jẹ́ ara ìdùnnú yi. Ìyàtọ̀ tí ó wà láàrín awa ati olúwa ti ó ga jùlọ ni wipe, òun kò ní gbèdéke ṣùgbọ́n àwa kéré. Ní pípéye, a jẹ́ ọ̀kan na pẹ̀lú RẸ̀, ṣùgbọ́n o ṣeni láànú wípé a ti gbàgbé ẹnití àwa jẹ́. A níláti gbìyànjú ki òye òtítọ́ yi yé wa. Kí a máṣe jà pẹ̀lú àwọn ẹlẹ́sìn míràn. Ìfẹ́ ẹ̀sìn tòótọ́ gbogbogbò, eyiti kò ní ìkejì. A nilati fẹ́ràn ọlọ́run ati ara wa pẹlu, nipa bẹ́ẹ̀, àwọn eniyan lè gbé pẹ̀lú ìdùnnú láyé yì.

ÌFẸ́ NÍ BÍ Ó TI RÍ

Vedas ṣe àlàyé wipe ẹlẹ́dà ní ìṣẹ̀dá tí ó lè paradà tí o sì ní pípéye tí ó sì nṣe àwọn ohun ara. Ó jẹ́ ẹnití o wu ènìyàn tí ó sì lè ṣe ohunkohun. Kò ṣeé pín, bẹ́ni kò ní ẹnìkejì. Bí o tilẹ̀ jẹ́ ọ̀kan, tí o sì jẹ́ ohun gbogbo, ó jẹ́ ènìyàn. Ọlọ́run: ẹlẹ́dà, ẹnití ó dá ayé yì: - ẹnití ó nṣe nkan, òun ni ó nṣe ayé yi, àti wípé- olùba-nkan – jẹ́, ẹnití ó ba ayé yì jẹ́. Ó ntọ́ju, ó sì nṣe àtìlẹ́hìn fún gbogbo ayé. Àwọn

ẹni ẹ̀mí bi Srila Vyasadeva, Narada Muni ati oluwa Brahma ti sọ fún wa pé ó rẹwà pẹ̀lú àmúyẹ ní ọ̀nà ẹgbẹ̀rún lọ́nà ẹgbẹ̀rún.

Tí o bá ri bí bàbá ṣe rí, ọmọ rẹ̀ na yio ri bí ó ṣe rí. Tí kò bá sì rí bí bàbá ṣe rí, tàbí kí ó péye, bẹ́ẹ̀ná ni ọmọ kò ní rí bí ó ṣe rí tàbí péye tàbí kí ó tilẹ̀ wà láyé.

Ó lè dàbí ẹnipé nígbàmíràn, a má nṣe apejuwe Ọlọ́run gẹ́gẹ́bi ẹniti kò ní bí ó ṣe rí, ṣùgbọ́n nígbàtí àwọn ìwé mímọ́ míràn bá wípé kò ní "ìjúwe" nwọ́n nsọ wípe kò ṣee ṣe apejúwe, kò ní pípéye, kò ní àwọn ẹ̀yà. Ìjúwe àti àwọn ẹ̀yà rẹ jẹ́ ti ẹ̀mí: ó jẹ́ alágbára jùlọ, nípa bẹ́ẹ̀, ó ní agbára láti ní bí ó ṣe lè rí. Tí kò bá ní bí ó ṣe rí, tàbí kí ó péye, tàbí ni agbara ati aanu, kò ni jẹ́ ohunkóhun. Kò ni lè ràn wá lọ́wọ́ tabi gbọ́ àdúrà wa, kò ní ní ọ̀rọ̀ lati sọ tàbí fun wa ni Alafia ayeraye. Awa ko Gbagbọ nínú Ọlọ́run tí kò ní àánú, agbára ati tí ó péye. Tí kò bá ni ìpéye gẹ́gẹ́bí aanu, kò ní sí ìdí láti máa sìn í.

Nínú Bíbélì àti Kùránì, o wa nibẹ pe ó ní bí ó ṣe rí. Bibeli sọ pe "Ọlọ́run dá ènìyàn ní àwòrán ara RẸ̀" tí kò bá ní bí ó ṣe rí, kíni ìdí tí Bíbélì ṣe wí bẹ̀? Àwòrán RẸ̀ lè yípadà; kì Í ṣe ẹ̀dá ènìyàn. Ó ní ara ti ẹ̀mí láti ibití ó ti dá ènìyàn. Wọ́n tún sọ pé Jésù Krístì jẹ́ ọmọ Ọlọ́run. Tí Ọlọ́run bá ní ìjúwe, ọmọ rẹ̀ na níláti ní ìjúwe. Lótìtọ́, ó ní ìjúwe tí ó rẹwà jùlọ. Ó ni gbogbo àmúyẹ ti o dara, ó pé pẹ̀lú agbára gbogbo.

Kùránì wipe: " Inallah kalaka mein Suratibi- Ọlọ́run tàbí kudda, ní ìjúwe láti bí ó ṣe ri ni ó fi dá ènìyàn", Gbólóhùn Suratibi túmọ̀ si "ohun ti a le ṣe ìjúwe rẹ̀" Allah na tumọ si "Ẹniti ó tóbi jùlọ". Gbogbo ọ̀run àti ẹ̀dá wa nínú RẸ̀ kò sí ohun tí a lè fi wé Allah ti o tobi julọ. Ìwòye Vedic Ọlọ́run fi idi òye yi múlẹ̀ ti o tun wipe ẹlẹ́dà ti o tobi jùlọ yi, Olúwa Krsna jẹ́ ẹnití ó tóbi jùlọ tí ó sì kéré jùlọ.

Gbólóhùn "àiní ìjúwe", "àiní ìjúwe" àti "àiní ẹ̀yà" tí a lò láti júwe Ọlọ́run nínú àwọn iwe mimọ wá láti inu gbòngbò ọ̀rọ̀"bí ó ṣe rí", "ìpéye" àti "ẹ̀yà". Láìsí ìgbékalẹ̀ pé ohun kan ní bí ó ṣe rí kò lè sí ìrònú wipe ohun kan wà láìní bí ó ṣe rí. Opin gbogbo rẹ̀ wá ni pé, ẹlẹ́dà yi ní bí ó ṣe rí, ó péye ó sì ní ẹ̀yà; tí ọ̀kan lára àwọn àmúyẹ̀ wọ̀nyí sì níláti jẹ́ àánú. Àánú rẹ̀ pọ̀ bẹ́ẹ̀ tí ó fi da gbogbo ayé-lati lè tẹ́ awọn ifẹ́ àìgbọ́n wa lọ́rùn kí a si gbadun wọn láiní ọwọ́ Ọlọ́run nínú.

## LÁÌSÍ ÌFẸ́ NÀ

Nígbàkan, ọkùnrin kan wà ninu igbó, ó gbọ́ ohun àmọ̀tẹ́kùn. Bí ó ṣe nfi ìbẹ̀rù sáré lọ ni ojú rẹ̀ nwo ọ̀tún àti òsì láti rí ibití ó lè sá pamọ́ si. Níkẹhìn, ó ri kanga ti kò ni omi kan. Àwọn koriko ti hù sí ori rẹ̀ ati ní ẹ̀gbẹ́ kànga na ni igi kan hù sí. Ó di ẹ̀ka méjì ara igi na mú láti sọ̀kalẹ̀ si inú kànga nà, pẹ̀lú ìtùnú wípé àmọ̀tẹ́kùn tí ó nle kò ní lè rí òun nínú kànga gbígbẹ nà. bí ó ṣe nsọ̀kalẹ̀ lọ sí inú

kànga ná ni ó rí awọn ejò ní ìsàlẹ̀ kànga na. Àwọn ejò olóró wọ̀nyí gbé orí sókè láti bu arákùnrin yi jẹ.

Bí ó ṣe rọ̀ mọ́ àwọn ẹ̀ka igi méjì ni o ri wípé ìdàmú rẹ̀ ti pọ̀ si. Ní ìsàlẹ̀ kànga ni àwọn ejò olóró, ní òkè ni àmọ̀tẹ́kùn ìbẹ̀rù tí ó fẹ́ pá jẹ. Ìbẹ̀rù nlá bòó.

Lẹ́hìn èyí ni àwọn eku méjì- ọ̀kan dúdú, ọ̀kan funfun- wọ́n bẹ̀rẹ̀ sí jẹ ẹ̀ka igi tí ọkùnrin yí rọ̀ mọ́. Èyí túmọ̀ sí pé láìpẹ́, wọn ó jẹ ẹ̀ka nà tí kò sì ní lè gba òun dúró mọ́ tí òun yío sì jábọ́ sí inú kòtò tí àwọn ejò olóró wà. Láti lè bọ́ nínú ewu yi ó níláti gòkè padà sókè sí ẹnu àmọ̀tẹ́kùn tàbí kí ó bọ́ si ẹnu ejò olóró. Èyí kéyì tí o bá fẹ́ ṣe, ìrírí rẹ̀ kò lè rọrùn.

Nínú ipò ewu yi, ọkùnrin na ṣe akiyesi afárá oyin ní ori igi tí ó di ẹ̀ka rẹ̀ mú. Nitori igi na ti nmi, oyin bẹ̀rẹ̀ sí kán sílẹ̀, èyí nwáyé ní ẹ̀gbẹ́ ojú rẹ̀. Ó wá lo àkókò kékeré yi láti gbádùn ara rẹ̀ nípa lílá oyin na. O bẹrẹ sí gbádùn adùn oyin wipe “oyin na dun pupọ! Ó dùn pupọ”. O ni ayọ̀ díẹ̀, ó gbàgbé pátápátá inú ewu tí ó wà.

Gbogbo àpèjúwè ìtàn yí sọ nipa ayé tí a wà. Ọkùnrin inú ìtàn yí sọ nípa gbogbo ọkàn tí ó wà láyé yì. A wà ní ipò ewu, tí a lè kú nígbàkugbà tí kò sí ọ̀nà àbáyọ nínú àwọn ohun ti a nṣe. Àwọn ejò olóró wọ̀nyí túmọ̀ sí oniruuru ìṣòro ti ó nba wa léraléra bí ìgbì omi òkun. A ma nrò pé, “Èyí ni ìṣoro ìkẹhìn mi. Inú mi yió dùn lẹ́hin eyi” ṣùgbọ́n nígbàmíràn, eyiti yio tẹ̀le yío tóbi ju ti ìṣáajú lọ, nigbamiran, ọ̀pọ̀ ìṣòro tàbi ìdàmú yio rọ́ lu ara wọn lẹ́ẹ̀kannà – márùn tàbí mẹ́fà lẹ́ẹ̀kannà. Ní òkè kànga ni àmọ̀tẹ́kùn ndúró, èyítí ó dúró fún ikú, tí ó dúró de gbogbo wa láye.

Awọn ẹ̀ka méjì wọ̀nyí dúró gẹ́gẹ́bí ohun tí a nṣe nítori àwọn ìdàmú tí ó nbá wa – yálà rere tabi búburú, mímọ́ tàbí àìmọ́. Lapapọ, àwọn ìṣe wọ̀nyí nwáyé ni gbogbo ọjọ́ ayé wa, tí ó sì ndínkù lórè kóòrè. Eku dúdú dúró fún ìgbà òru tí eku funfun sì dúró fún ìgbà ọ̀sán. Inú wa yió dùn nígbàtí ọjọ́ míran bá dé tí ó sì lọ, lótìtọ́, lílọ bíbọ̀ àwọn ọjọ́ túmọ̀ sí pé ọjọ́ ayé wa nlọ díẹ̀díẹ̀.

Lárín ọ̀pọ̀ ìṣòro àti ewu, afárá oyin kan yío kán sí ahọ́n wa, èyí tí a lè fi wé ìgbádùn ìdùnnú díẹ̀ tí a rí pẹ̀lú àwọn ọ̀rẹ́, mọ̀lẹ́bí ayé yì.

## WÍWÁ ÌDÙNNÚ

Gbogbo ẹ̀dá alàyè ni wọn nlàkàkà ṣe làálàá lati ní ìdùnnú ayeraye ṣùgbọn gẹ́gẹ́bí Vedas ṣe ṣàlàyé, àwọn ohun ayé yi kò lè fún wa ní ìdùnnú kò ní fi ṣe irú ipò tí o dìmú, kò lè fún ọ ní ìtẹ́lọ́rùn. Tí o bá tilẹ̀ jẹ́ ilú mọ̀ọ́ká, o tún máa wá nkan tí yío fi kún ayọ̀ rẹ.

Àwọn àrẹ àti olórí àwọn orílẹ èdè nlá kò ní ìtẹ́lọ́rùn. Ní gbogbo àkọsílẹ̀, ó fihàn pé àwọn alagbára ènìyàn gẹ́gẹ́bí Napolion ati awọn ọba ati awọn ọba bìrin ìlú òyìnbó, faransé ati Jamaní, ní àìdùn inú ní àìnífiṣe ipò ànfàní tí wọ́n wà. Ní àkókò ọ̀làjú yì, a nrí èyí nínú ayé àwọn ọmọba bìrín Diana ati Bill Clinton àti bẹ́ẹ̀bẹ́ lọ. Ìdùnnú díẹ̀ tí a ri láye yi wà fún ìgbà díẹ̀ tí ó sì dàpọ̀ mọ́ ìjìyà. Kò tẹ̀síwájú bẹ́ni kò wà títí lái, bẹ́ni kò pẹ̀ kò sí mọ́. láti àyè tí o kéré jùlọ dé èyítí ó ga jùlọ, oniruuru idamu lo wa laisi idunnu ayeraye.

Kò si ọkàn tí ó ní àjọṣe pọ̀ pẹ̀lú ohun ti ara tó lè ní ayọ̀. Ayé ènìyàn wa fun àti wá ọ̀nà kúrò nínú àhámọ́ ara yi, eyiti ó wà láti darúgbó kí ó sì kú. A fẹ́ ní ayọ̀ nípa títẹ́ ara yi lọ́rùn, ṣùgbọ́n ọjọ́ ogbó tètè ndé tí a sì npohùnréré ẹkún. Ìdùnnú tí a nni kìí ṣe ojulowo idunnu. Ó jẹ ògidì ìdàmú. Òye kò yé wa wípé ọkàn èyítí ó yàtọ̀ sí ara ati ẹ̀mí jẹ́ nkan ti ẹ̀mí, tí ó wà títí ayé tí ó sì ní ìmọ̀ ati Alafia nìkan ni ó lè fún wa ní ìtẹ́lọ́rùn tòótọ́- èyí tí Í ṣe ẹ̀mí Ọlọ́run àti ìbáṣepọ̀ ìfẹ́ wa pẹ̀lú RẸ̀ .

Lóde òní, a nṣe ọ̀pọ̀ ìdásílẹ̀ ati ìwádì ti àwọn abala ìṣègùn, ìrìnà ọkọ̀ àti ìbára ẹni sọ̀rọ̀. Ó rọrùn láti lọ láti igun aye kan lọ si omiran larin wakati díẹ. A le joko si inu yara wa ki a si maa wo ohun ti o nṣẹlẹ̀ ni agbaye: a le wo eré ìdárayá bi o ṣe nlọ ni Australia tabi India, a tun lè ri àrẹ Amẹ́rikà bi o se nsọ̀rọ̀ ninu ile ijọba ni Washington. Ti ẹnikan ba si ni ipenija ojú, àwọn onímọ̀ ìṣegùn lè ṣe àtúnṣe ojú na lati ara ojú òkú tí ó ti kú.

Ṣùgbọn pẹlu gbogbo iwọnyi, ati awon itẹsiwájú miran, ijiya npọ fun awọn eniyan ju ti tẹ́lẹ̀ lọ, ko si ọ̀nà lati dena dídarúgbó, tàbí ikú, bẹẹni a ko tii lè dènà ogun àti ìgbésùnmọ̀mí tabi ìtànkálẹ̀ àwọn aisan. Awọn aisan titun tun ndide. Itẹsiwaju ìmọ̀ ijinlẹ ati imọ ẹ̀rọ kò mú idunnu wa fun wa. Níṣe ni a kàn nbẹ̀rù, ti a nmọ ohun ti ara wa nìkan ti a si nlepa ohun ti ara.

Kini idi ti ìmọ̀ ijinlẹ òde òni ṣe nkùnà? Idí ni wípé kò dagba tó. Awọn onímọ̀ ìjìnlẹ̀ kò rí ọkàn èyítí ó lè yípadà, wọn kò tilẹ̀ lè rí ẹ̀mí. A rò wípé a ti dagba tó nítori idagbasoke imọ ẹ̀rọ, ṣùgbọn ohun ti a ti ṣe ni láti sọ ohun ti a nílò nípa ti ara di púpọ̀ ti a si dágunla si awọn nkan ti ẹ̀mí. a kò bìkítà lati fẹ́ràn Oluwa ti o tobi julọ nipa bẹ́ẹ̀ a ko ní ìfẹ́ tooto ati ìfẹ́ si ara wa.

A ni ìgbẹ́kẹ̀lé ninu awọn ajá àti ológbò wa ju àwọn ẹbí ati ọ̀rẹ́ wa. Àwọn ọkọ ati ìyàwó kò wà papọ̀ tí ìkọ̀sílẹ̀ sì di pípọ̀. Awọn òbi nkọ àwọn ọmọ wọn sílẹ̀ tí àwọn ọmọ na sì nkọ àwọn òbí wọn sílẹ̀.

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn ni wọ́n nífẹ̀ lati tẹ́ ara àti ọkàn wọn lọ́rùn.

Àwọn tí wọn fẹ lati fi ètò sí ọmọ bíbí, àjàkálẹ̀ àrùn, dídarúgbó ati ikú lè kọ́ láti lo ànfàní àṣà Vedic. Kíkọ́ ẹ̀kọ́ ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ òde òní kò ní ràn wá lọ́wọ́. Nigbati imọ ìjìnlẹ̀ bá dàgbà dé aye ayẹyẹ lásán àwọn eniyan lè wá máa tẹ̀ sí ètò

ìdarúgbó àti ikú ṣùgbọ́n láti le de ìpele yi, àwùjọ òde òni níláti kọ́ ẹ̀kọ́ láti ọ̀dọ̀ àṣà vedic wa.

## ÌBÉÈRÈ PÍPÉ.

Vedas sọ ìtàn atijọ kan. "Ẹnìkan wà ni igbakan ti orukọ rẹ̀ njẹ́ Yijnavalkya ẹniti ó wà nínú ìgbìmọ̀ ọba gbajúgbajà Janaka. Ó ní ẹ̀kọ́ Vedas gidigidi, ẹniti ó mọ̀ nípa ìwàláàyè ọkàn àti ẹ̀mí tí ó ga jùlọ ninu ara.

Yajnavalkya ni iyawo méjì, Maitreyi ati Karyaya. Nigbakan ni ọjọ́ ogbó rẹ̀, ó pe awọn iyawo rẹ̀ mejeeji, o sọ fun wọn pe "A ti jẹ alájọgbe fun ọ̀pọ̀ ọdún. Mo ti kó ọ̀pọ̀ wúrà àti màlú jọ, mo si ti fun ọ̀kọ̀ọ̀kan yín ni awọn ọmọ. Mo fẹ́ pin ogun mi fun yin ki inu yin bà lè dùn ni iyókù aye yin. Lẹ́hìn tí mo bá ti ṣe èyí tan, ẹ jọ̀wọ́ ẹ jẹ́ kí nlọ sí inú aginju láti ṣe àṣàro tí ó jinlẹ lori ẹniti ó njẹ́ Ọlọ́run nlá".

Bi o ṣe gbọ́ èyí, inu Karyaya dùn ó sì wípé: " afojusun rẹ, èyítí o ṣe iyanu ni láti lọ ṣe àṣàrò lórí Olúwa tí ó ga jùlọ. Iwọ ni ọkọ mi, èmi yío sì ràn ọ́ lọ́wọ́ lati ṣe èyí"

Èsì Maitreyi yàtọ̀, Ó wípé, "Mo ni ìbéèrè, lẹ́hìntí o bá ti dáhùn ìbéèrè mi o lè lọ pẹ̀lú ọkàn ìdùnnú. Ò nlọ sí inú aginju nítori àìní ìtẹ́lọ́rùn pẹ̀lú gbogbo wúrà ati dúkìá tí o ti kó jọ lọ́jọ́ ayé rẹ tàbí pẹ̀lú àwọn aya rẹ, àwọn ọmọ àti ọ̀rẹ́, ṣé o wá rò pé àwọn nkan wọ̀nyí yío mú inú wa dùn?"

Yajnavalkya dahun: Nitootọ̀ aya tí ó fi ara jì fún mi ni o jẹ́. Pẹ̀lú ìbérè rẹ yi, o ti mú inú mi dun. Idahun sí ìbérè yi di ohun tí a nsọ nipa rẹ̀ ní gbogbo Vedas. Wúrà àti dúkìá kò lè fún wa ní ìdùnnú tòótọ̀. Ipò ni àwùjọ, ẹ̀kọ́ kíkọ́, ipò, ọ̀rẹ́ àti ẹbí kò lè fún wa ní ìdùnnú tòótọ̀. Owó àti ohunkóhun tí o lè fi rà láyé kò lè fún wa ni ohun ti à npòngbẹ rẹ̀. Awa jẹ́ ara ati apa Oluwa àgbà nítorí nínú RẸ̀ ni agódo ìdùnnú wà. Nitorina nínu rẹ̀ nìkan ni a ti le ri idunnu. Ojúlówó ìdùnnú ni tí a bá nsìn, ṣùgbọ́n idunnu tí a ntọrọ láyé yi kéré, ó sì lè parun. Olúwa Krsna jẹ́ ọkàn tí ó ní ibaṣepọ̀ tí ó dùn, ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ èyí tí ó ga jùlọ. Òun ló lè fún wa ní ìtẹ́lọ́rùn; nípa bẹ mo fẹ́ lọ báyì sí aginjù láti lọ gbàá.

## IPA Ọ̀NÀ SÍ ÌDÙNNÚ

Tí a bá fẹ́ ní òtítọ̀ ayọ̀, a níláti lọ́wọ́ si sisin Ọlọ́run. Ni Vedas, a npe ìlànà yi ní bbakti-yoga, tabi àsopọ̀ pẹ̀lú Oluwa ti o ga julọ, nipa sinsin in. Nipa ìlépa idunnu RẸ̀ ni àkọ́kọ́, láìṣe àníàní, ìwọ yio ni idunnu pẹ̀lú alaafia. Kìíṣe ìpalára

fun àwọn ẹ̀dá míran, yálà ẹranko tabi eniyan , nipa bẹ́ẹ̀ o lè gbé ìgbé ayé Àláfíà pẹ̀lú gbogbo eniyan.

Ìfarajì fún Ọlọ́run ní ipilẹ ìtẹ̀síwájú méjì: Ipele ìgbésẹ̀, Ipele ìtanijí nínú ẹ̀mí àti ipele ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ ìdùnnú tí a npè ní ìfẹ́ tí ó mọ́.

Láti ní ìfẹ́ tí ó mọ, a nilati bẹ̀rẹ̀ ní ìpele ìgbésẹ̀. Ni aye ìjà àti ṣíṣe ojú ayé, tí a npe ni kali yuga, ìṣe ẹ̀mí tí ó lágbára jùlọ ati ètò tí ó dára jùlọ láti ni ayọ̀ ni láti maa fi orukọ oluwa ti o ga julọ kọrin. Orukọ Rẹ̀ kò yàtọ̀ si òun tìkara rẹ̀ tí ó sì ní gbogbo agbara àti ohun didun gbogbo. Ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ èyí yío wáyé ni ìpè ìfẹ́ tí ó mọ́. Kíkọ orukọ́ mímọ́ Ọlọ́run lórin yío wẹ ọkàn mọ́ kúrò nínú gbogbo ìfẹ́ òdì tí yío mú ìdákẹ́rọ́rọ̀ wá àti láti so pọ̀ mọ.

Àkọsílẹ̀ Vedic ti o njẹ́ kali- santarara upanisal wípé: “Ní ayé ì̀jà ati ìṣe ojú ayé yi, ẹyọ ọ̀nà àbáyọ ni kíkọ orúkọ mímọ́ olúwa ní orin. Kò sí ọ̀nà míràn. Kò sí ọ̀nà míràn. Kò sí ọ̀nà míràn. Kò sí ọ̀nà míràn. A lè kọ àwọn orukọ́ Olúwa lórin báyì:

| | | | |
|---|---|---|---|
| Hare | krsa | Hare | krsna |
| Krsna | krsna | Hare | Hare |
| Hare | Rama | Hare | Rama |
| Rama | Rama | Hare | Hare |

ẸWÀ ÈDÈ ÀTỌ̀RUNWÁ

Omi, atẹ́gùn ati ohun gbogbo ni yio di àdàlù ní àwọn ọjọ́ yì. Gẹ́gẹ́bí àwọn òkun ṣe ní àdàlù nkan olóró, nípa bẹ yío di májèlé fún ẹja àti àwọn tí wọn njẹ ẹja, àwọn ohun èlò àti inú atẹ́gùn pàápàá àwọn eniyan má nfọ́n májèlé sí afẹ́fẹ́ láti pa àwọn kòkòrò, nípa bẹ́ẹ̀ wọn yío sọ àwọn ounjẹ ati àwọn tí ó njẹ ounjẹ na di ẹniti o njẹ májèlé. Bẹ́ná ni àwọn ìró tí ó nmilẹ̀ gẹ́gẹ́bi èébú, ìdojúkọ àwọn ẹlòmíràn, ìjà àti bẹ́ẹ́bẹ́ lọ, àti nítòótọ́, èyíkéyì ohun èlò tí ó nmilẹ̀ lè sọ ọkàn, ọgbọ́n àti ọkàn gbogbo eniyan láyé di èyítí ó ti ní májèlé. A lè gbógunti àdàlù àti ìrora ohun olóró yi nípa kíkọ orin Hare krsna.

A lè ṣe àpẹrẹ adágún omi nlá. Tí o bá mú òkúta tí o sì jùú sí inú omi nà, rírú omi nà yío kan gbogbo etí adágún omi nà. Ayé dàbí adágún omi na. kíkọ orin Hare krsna, Hare krsna, Hare krsna Krsna, Krisna Hare Hare, Hare Rama Hare Rima Rima Rima Hare Hare yio di ọ̀pọ̀ ìró omi yío dúró nínú mímì ti ẹ̀mí.

Bí omi ná ṣe nmì, yío kan ohun gbogbo lára, títí dé òpin ayé – tí ó nlọ síhìn sọ́hùn tí ó sì n sọ gbogbo ayé di mímọ́ kúrò nínú àdàlù.

Olúwa krsna jẹ́ ohun alágbára tí kò ṣeéṣe àlàyé rẹ̀. Ó lè dá gbogbo aye lárín ìṣẹ́jú ààyá kí ó sì tún bàá jẹ́, ó tún lè dá ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ayé. Ó ti lo gbogbo àánú, agbára àti ọ̀rọ̀ tí ó wà nínú àwọn orúkọ RẸ̀. Nípa bẹ́ẹ̀ wọ́n di alágbára nlá. Kíákíá wọ́n lọ kákiri gbogbo ayé gẹ́gẹ́bí ìró tí ó nmì tí àwọn nkan olóró májèlé yío pòórá.

Àwọn igi, àfòmọ́, ẹranko àti àwọn kòkòrò kò lè sọ̀rọ̀. Èdè wa kò yé wọn, síbẹ̀ gbogbo ènìyàn. Kìí ṣe ẹ̀dá ènìyàn nìkan, ṣùgbọ́n gbogbo ẹ̀dá ní gbogbo àgbáyé yi – ni orúkọ alágbára mímọ́ yi yío kàn lára, yálà wọ́n mọ̀ọ́ lára tàbí bẹ́ẹ̀kọ́. Tí ènìyan bá ṣèèṣì tàbí mọ̀ọ́mọ̀ fi ọwọ́ kan iná, yío mọ̀ọ́ lára. Bẹ́ná ni àwọn orúkọ mímọ́ yi yío ru ìfẹ́ rẹ sókè yío sì ṣe ìwẹ̀nùmọ́ gbogbo nkan alàyè, yálà wọ́n mọ̀ tàbí wọn kò mọ̀. Àwọn igi, koríko àti àwọn eniyan yio ni anfani nigbati wọn bá gbọ nípa Krsna tí àwọn ẹ̀dá nínú igbó yío máa gba òmìnira díẹ̀díẹ̀ kúrò nínú ìjìyà.

Tí a bá nkọọ́ sókè, gbogbo ọgbọ́n wa yio di mímọ́, kò sì ní sí ohun àbùkù tàbí ìrántí ìbànújẹ́. Nípa àwọn ohun ti ara, a le má lè ṣe àkóso àìní, ìdùnnú àti àwọn èrò tí ó ní ànfàní èyí tí ó nwọ inú ọkàn wa, ṣùgbọn a lè ṣẹ́gun wọn pẹ̀lú ìrọ̀rùn nípa kíkọ orin. Díẹ̀díẹ̀ ọkàn wa yío máa di mímọ́ nípasẹ̀ orin na nígbàna ni a ó ṣe àwárí ohun tí a fẹ́- ọkàn àwọn ọkàn wa- òun ni olúwa krsna. Nípa bẹ, tí a bá sìn ín, àwọn àti gbogbo ayé yio jẹ ànfàní rẹ̀.

Sri Srimad Bhaktivedanta

Narayana Gosvami Maharaja

Láti inú ìkáànú rẹ̀, Srila Narajana Gosvami maharaja fi ara hàn láyé ní ọdún 1921 ni Biha India, ni ìletò kan ti orukọ rẹ̀ njẹ́ Tewa ripur.

Ẹnití ó dá ara rẹ̀ lójú gẹ́gẹ́bí ọmọ lẹ́hìn arọ́pò aṣíwájú mímọ́ tí ó padà sọ́dọ̀ Olúwa. Krsna fún rara rẹ̀, Srila Maharaja ni aṣíwájú ọmọ ẹ̀hìn aṣíwájú rẹ̀ nínú ẹ̀mí Srila Bhakri , Prajinana Kesara Gosvami Maharaja àti olùkọ́ rẹ̀ nínú ẹ̀mí, ògo Srila A.C. Bhakrivedanta Svami Maharaja. Oníwàsù àgbáyé ìtanijí Krsna.

Olùkọ́ tí ó dájú fún àwọn ìwé ọgbọ́n ìjìnlẹ̀ tí ó nṣe ìyápadà tí à npè ní Vedas Srila Nayana Maharaja tí a ti ṣe ìtumọ̀ tí a sì tẹ̀ jáde sí èdè òyìnbó àti ọ̀pọ̀lọpọ̀ èdè míràn tí ó sì ti nfún ọ̀kẹ́ àìmoye ènìyàn ní ìyè titun àti ìdàgbà nínú ẹ̀mí?.

Srila Narayana Maharaya jẹ́ ẹnití gbogbo ayé mọ̀ nípasẹ̀ ipa ribiribi tí ó kó nínú ìtẹ̀síwájú ìfẹ́ Ọlọ́run àti ìṣe arákùnrin àgbáyé.

Ní oṣù kejìlá, ọjọ́ kọkàndínlọ́gbọ̀n ọdún 2010, ó parí ìrìn àjò rẹ̀ láyé yì tí a kò sì ri mọ́ nínú ara ṣùgbọ́n àwọn ìdánilẹ́kọ̀ rẹ̀ yío má tàn si gẹ́gẹ́bí ìmọ́lẹ̀ láti máa tọ̀ wa ní ọ̀nà asáré mímọ́.

Gbogbo wa jẹ́ ọmọ aláyọ̀ ẹnití ó ga jùlọ. Kí a gbìyànjú láti ní òye yi. Kí a máṣe jà pẹ̀lu àwọn ẹlẹ́sìn míràn.

Ẹyọ ẹ̀sìn òtítọ́ ọ̀kanṣoṣo ni ìfẹ́, èyítí kò ní àfijọ, kí a gbìyànjú láti fẹ́ràn ara wa, báyì ni gbogbo ènìyàn ṣe lè gbé pẹ̀lú ìdùnnú láyé yì.